# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 866 LAGOS SATURDAY APRIL 21— APRIL 27 KOBO MEJI (2D) 1963


**Salamotu Pade Agbako**

# Alikali Ilorin Ni Ki Nwon Na Obinrin Ti O Gbe Oyun Oko F'ale Ni Ogorun Bilala

ILỌRIN–Obinrin ara Ilọrin kan ti nwọn npe ni Salamọtu Alakẹ pade agbako lọdọ adajọ Kotu Alikali kan ti orukọ rẹ Mallam Umoru Bida ti o da ẹjọ fun ni ọsan ijẹta wipe ki nwọn na ni ẹgba bilala fun iwa agbere ti o hu, ti gbe oyun ọkọ fun ale rẹ atijọ.

Saka Ajadi ti ṣe ọkọ Salamọtu nisisiyi paapa fi ara gba ninu ọrọ na, nitoripe adajọ alikali yi ni ki on na lọ gba ogorun bilala ni ọdọ awọn dongari ọlọpa ni iwaju Mọsalasi Jimọ Ilọrin.

Onirohin wa ni gẹgẹbi on ti gbe ọrọ ẹjọ na ti nwọn gbe wa si Kotu Alikali, ọrọ na ki ṣe ọrọ igba yi, o to ọdun mejilelogun nisisiyi ti ọkunrin kan, gbe Suberu Ayinla ti Salamọtu yi ni iyawo, o si bi ọmọbinrin kan fun un. Ọmọ ti ọmọbinrin na bi ti lọ si ilẹ ọkọ nisisiyi, ṣugbọn ni aipẹ yi ni ọrọ kan ọrọ, ti Salamọtu ni Suberu kọ ni on bi ọmọ na fun, ale on ọjọ kini ti nwọn npe Saka Ajadi ni on bii fun.

Adajọ Alikali ti nwọn gbe ọrọ na lọ si iwaju rẹ ni on ko gbọ iru ọrọ jegbejegbe bayi ri. O ni ọbaiyẹ ni awọn nwọnyi.

Malam Umoru Bida tiṣe adajọ Kotu Alikali na ni ṣẹria ti Kurani wi ni on yio da fun wọn.

## Igba Enia Ni Sardauna Mu Lo Si Meka

KANO—Igba enia ni Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto mu lọ si ilu Mẹka ni ana ode yi. Ni ilu Kano nibi gbogbo wọn ti wọkọ baalu ti Sardauna na haya fun irin ajo na.

Awọn Ọlọla ọlọla, awọn Alikali adajọ kotu, awọn Minisita alamojuto iṣẹ Ijọba, awọn ijoye Hausa, awọn balẹ igberiko pẹlu awọn alufa ile ikewu ni Sardauna na ko lọ si Mẹka.

Ki o to kuro ni Kaduna, awọn ọmọlehin rẹ ṣe adura fun un wipe alọbọ ni Mẹka na a jẹ fun un, nwọn si sin in de eti Zaria ninu mọto wọn ki nwọn to pada lẹhin rẹ.

Ni Eko, ni ijẹta awọn irinwo enia ati ọkunrin ni nwọn tẹ tẹ ọ... le i lọ si Mẹka pẹlu awọn ti akọkọ ti nwọn ti lọ. N... u awọn ti akọkọ na ni Ọgbẹni Ibo kan ti o di Im... e wa. Mo gbọ wipe ọkunrin Ibo yi ni yio kọ jẹ ọmọ ilu Ibo kinni ti yio kọ lọ si ilu Mẹka ati Medina, lẹhinti o ba ṣe Hadji tan ni ilu mẹka o tun nlọ si ilu awọn ẹlẹṣin Imale miran bi Moroko, Lybia ati Lebanon ki o to pada wa si ile.

## Adajo Ju Tisa Tj O Gbe Owo Ilewe Lo Sewon

PORT-HARCOURT — Adajọ-agba kan, Ọgbẹni Victor A. Savage sọ olori awọn tiṣa ilewe kan ti o njẹ Marcus Dappa sẹwọn ọdun mẹta nitori owo ilewe o ji gbe ni ilu kan ti nwọn npe ni Ogbabere nibi.

Ẹjọ ti awọn Ọlọpa ba ... daran na ro niwaju adajọ ni pe awọn alamojuto ilewe ti o ti nkọ wọn l'ẹkọ ni Niger Delta ko ẹgbatala ponun o din diẹ logorun ponun(£2,058 :6s:5d) fun u wipe ki o fi san owo oṣu gbogbo awọn tiṣa ti nwọn nṣe iṣẹ labẹ rẹ. Kaka ki o lo owo na lọna nwọn ni ko lo o fun, nkan miran ni o lo o fun.

Gbogbo awọn olukọ ti o wa labẹ rẹ ni ko ri owo oṣu gba, nigbati nwọn bi lere, o ni on fi owo ṣe anu fun awọn kan ti awọn ni ki on ya awọn ni.


**LAGOS RACE CLUB**

**LAST DAY**

**Easter Race Meeting**

TODAY

First Race at 3.30 p.m.

The Guest of Honour are
Hon. & Mrs. T. O. S. BENSON

COME ONE COME ALL.

Hon. Secretary,
Lagos Race Club

## Iwe Aba Lori Oti-Bolugi Wo'mi

EKO — Gbogbo ero awọn ara Ijaw (Ijo) ati Isobo ti nwọn nfẹ fi ọti-bolugi pipọn se iṣẹ oojọ wọn, ti nwọn ni ki awọn kan ninu awọn ọmọ ile Igbimọ asofin bi awọn gbe iwe-aba wa, e ki awọn alakoso Ijọba gba wọn laye lati le ma pọn ọti na, ni areti wọn womi ni ijerin, nigbati awọn ti awọn gbe iwe-ẹbẹ nt le lo-wa tu nwọn lọfọ wipe awọn ile igbimọ na ko fọwọ kan iwe na rara.

Awọn ọmọ ile igbimọ aṣofin mẹfa ti nwọn sọwọ pọ lati gbe iwe-aba lori oti-bolugi na ce ile igbimọ aṣofin, ọkan ninu awọn mẹfa na ni Ọgbẹni E C Akwiwu, t ṣe igbakeji olori ile igbimọ na l'Eko.

Ato gbọ wipe ko nṣe wipe ọna ti iwe-aba wọn ni ei wọle tona ṣugbọn aye ni ko si fun awọn ikọ ti nwọn wa si ipade na lati fọwọ kan an. Nwọn ni gẹgẹbi ofin nwọn ni lati duro fun bi oṣu mẹta ṣ ako ti nwọn yio tun ṣe ipade tu n awọn Igbimọ aṣofin ki nwọn to le fẹnu kan ọrọ lori aba ọti-bolugi na.

Gbogbo awọn ọmọ Ijaw ati Isobo lọkunrin ati lọbinrin ni nwọn yọ aṣọ ti tu dara lọke leka ti nwọn pejọ si Ọdan l'Eko ki nwọn to tafọ ọrọ ọti na ti o wọ'mi fun wọn. Nwọn tun gbe ilu ilu wọn ti nwọn fe lu lọwọ bi ọrọ na ba bọ si wipe ki awọn ma pọn ọti bolugi na.

RECORDS of THE WEEK

78 R.P.M. at 7- each
P 82502 H
Omoelar Apala Special
By Dr. Ayinla
Apala
P 82032 H
Oja Iotuwokun
Osu
by Adebukola Ajao
and her Group
waka & Apala
45 RPM (Single
at 1/6 each
B 3729 F
Blueberry Hill
Maybelle
By Johnny Hallyday
TWIST

PHILIPS
of course...
— the records of the century —

# Ebun Egberun Meji Pelu Abo Ponun Fun O Ninu Osu July

### Awọn Ebun miran wa ti o le je pelu awọn iwe esu ti o ra lati fi owo pamo yi

Jakejado ile Nigeria ni awọn enia olorire mejidinlogọta nki ara wọn ku orire fun ti ebun ti nwọn ri gba ninu idibo orire ti AKỌKỌ ṢE FUN AWỌN TI O RA IWE EṢU IJỌBA ni ọjọ kini oṣu April. Ninu oṣu July ti mbọ ao tun ta irufẹ Orire bayi fun enia mejidinlogọta miran. IWỌ na paapa le jẹ ọkan ninu awọn Olorire ti yio jade ni asiko yi bi o ba ra ninu Iwe-Esu na NISISIYI Olotu alamojuto ile owo Ijọba so wipe awọn yio fi aye silẹ fun gbogbo awọn ti o ba ra ninu IWE-ESU ti oṣu April lati ni ẹtọ idibo Orire pẹlu ninu oṣu July.*

Eyini ni wipe gbogbo awọn ẹniti o ba ti bẹrẹ ni ọjọ Kẹta Oṣu December 1962 titi de ipari Oṣu April 1963, yio ni aye lati jẹ ọkan ninu awọn

### EBUN NLANLA TI AO TA NINU OSU JULY

A le ri Iwe-Esu yi ra ni gbogbo ibi iṣẹ Post Office tabi ni awọn ile ifowopamọ si (Commercial Bank) ni ponun kan, ponun mẹwa tabi ọgọrun ponun (£1, £10 & £100).

# MA SE JAFARA RA IWE-ESU TIRE LONI

*Oṣu meta ni a ni lati duro fun ki a to le ta orire Iwe-Eṣu yi ṣugbọn nitoripe awọn ọpọ enia ni wọn ti bẹrẹsi ni ifẹ si Orire ti akọkọ ta, Olotu Ile Ifowopamọ si gba wipe NINU ORIRE TI AO TA NINU OṢU JULY YI, gbogbo ẹniti o ba ti ra tirẹ lati inu oṣu April eyiyi ni wipe gbogbo awọn ẹniti a ba wipe ki o duro fun oṣu meji tabi jubẹlọ ni ao ta Orire tirẹ ni ọjọ kini oṣu July 1963.

# Bi Ere Sakara Se Bere . . .

Lati ọwọ ỌLALEKAN ỌNATADE

O to iwọnkan bi ẹdun mẹtadinlogoji nisisiyi ti nwọn bẹrẹ ere ijo ti nwọn npe ni Sakara nisisi ni ilu Yoruba.
Mo fẹ sọ diẹ nipa itan bi ere ati ijo na tiṣe bẹrẹ ni ilu wa nibi.

Ni ọdọ awọn Imale Ilọrin Yoruba ilẹ wa ni o ti bẹrẹ. Ibẹrẹ ere sakara na nidi pupọ.

## Awo Olugboun

Ṣe tẹlẹtẹlẹ awọn KIRIYO (Onigbagbọ) ni o kọ laju si a nkọrin sinu awo-Olugbohun (gramophone record), gbogbo orin ti awọn Kiriyo ọjọ na si nkọ si awọn awo-olugbohun yi koju ti orin ijọ Ṣọṣi wọn lọ, ko si orin a nṣe faaji nibẹ.

Ẹniti o ba ṣe faaji pupọ ni aiye na lọhun aṣa-enia ni nwọn mọ ọ si.

## Igbalaiye

Ṣe awọn agbalagba ni igba laṣọ, igba lẹwu, igba ni ọmọ bibi inu paapa; igba na wa yi pada were fun awọn ọmọ Imale ti nwọn mọ iwe ka. Ọpọlọpọ wọn ni nwọn wọ iṣẹ nile awọn Oyinbo Onisowo.

Nwọn nri owo ṣe lọpọlọpọ awọn miran nkọju mọ iṣẹ ọwọ wọn. Awọn ti Eko nyip pada, isẹ ngbe wọn lọ si Abẹokuta, awọn ti Abẹokuta nlọ si Ibadan awọn ti Ibadan nlọ si Ogbomọshọ ti Ogbomọshọ nlọ si Bida.

## Ilaju De

Oju awọn enia wa nla, nwọn wa ri wipe awọn ilu ti nwọn fi nṣere faaji ti o dabi bata-koto, gangan, ṣẹkẹrẹ ati bẹẹbẹ nilẹ wa wa ni ibomiran.

## Orin Molo

Awọn ara Ilọrin lo kọ

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

A won Iwe Asiko:

# Fifi Owo Pamo Si Banki

Iwe Alufa ATILADE

Ni igba laịlai, awọn enia ko nlo owo rara, ohun ti nwọn ba ni lọwọ ni nwọn nfi ṣe paṣiparọ fun eyiti nwọn ko ni, ti nwọn si fẹ. Eyi ni pe ẹniti o ni iṣu ti o si nfẹ epo lati se ọbẹ, yio mu diẹ wa ninu iṣu rẹ lati fi fun elepo, ẹniti yio fun u ni epo dipo iṣu rẹ. Ni akoko yi, awọn enia ama kọ aba tabi aka lati fi ounjẹ wọn pamọ tabi di igba ti nwọn fẹ ẹ fun iparọ tabi jijẹ fun ara wọn. Yio mu eyiti on ko fẹ ilo rẹ lọ si ọja, yio si gba owo dipo rẹ.

## Lati owo AKOWE

A mu owo yi lọ ra nkan ti o ba fẹ fun ile rẹ, ṣugbọn ni igba pupọ owo ti o gba lori rẹ pọ ju eyiti o na lọ. Owo ti o ku nilẹ yi pọ lọwọ ẹlomiran to bẹgẹ ti o jẹ pe nwọn ni lati wa ọna lati fi i pamọ dada ki o ma ba bọ s'ọwọ awọn ole. Olukuluku ẹniti owo ṣeku lọwọ rẹ bayi ni lati fi owo yi pamọ ni ọna ti yio fi ọkan rẹ balẹ de ọwọ aladugbo on ko le tẹ owo yi. Ọna ti ọpọlọpọ enia nlo ni lati lọ bo owo yi mọlẹ ni idi igi tabi sinu yara wọn, nwọn yio ṣe ami si ibẹ lọna ti o fi jẹpe awọn nikan ṣoṣo ni yio mọ amin na.

Nigba pupọ ni iru awọn owo bẹ nsọnu patapata. Nigbamiran ti iku ba de lojiji si awọn ti o fi owo yi pamọ, nwọn ko ni anfani lati fi aṣiri ibiti owo na wa han awọn enia wọn. Ni aipẹ yi, a sọ itan ẹnikan ti o nṣan ilẹ fun oko koko ti o si ri idi oru ti o yọ jade ni idi igi nla kan. O ti ada rẹ bọlẹ lati wo bi apadi ni on ri tabi odiadi ikoko. Si iyalẹnu rẹ, oru nla kan ni ti o wuwo rinrin.

Nigbati o gbe oru yi jade, ti o si yọ okuta ti a fi ba ni ẹnu kuro. Owo ṣile ni o ri ti o funfun pin i. Ẹniti

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

'Timi Gbowo Pada:

# Ofin Pajawiri Jabo

IBADAN — Adajọ Kotu, Ọgbẹni Olujide Shomolu ni Ibadan paṣẹ wipe ki awọn Olotu ile olowo-ori lọ da igba pọnun owo ori ti nwọn fi ofin pajawiri gba ni agba le lọwọ Oloye Rotimi Alade Williams ni ọdun ti o kọja pada fun un nitoripe ofin pajawiri ti nwọn fi gba owo na ko mu rọ rara.

Lọya Rotimi Williams ni o fi ọwọ ara rẹ pe awọn Olowori na lẹjọ si Kotu-ganrn wipe owo kan ti nwọn ṣiro mọ owo ori ti nwọn gba lọwọ un ko tẹ o n lọrun rara ati pe iwe ofin pajawiri ti nwọn fi gba owo na ko mu rọ nitori pe asiko ti n dele Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun wa lori aga ni o le ṣe ofin fun, ko gbọdọ kọja aye rẹ.

Oloye Rotimi Williams sọ fun adajo wipe gẹgẹbi ofin Adele Olotu Ijọba pajawiri ti kọja agbara ti nwọn fun un, ọna ti awọn Olowori si gba ko tọna.

O tun ṣe alaye fun adajọ bi on ti ṣe wahala to lati fi ikuna na han awọn igbimọ olowo-ori ni Ibadan, ti on si sọ wipe ki awọn da owo ti nwọn gba ni a-gba-le na pada fun on ti nwọn si kọ jalẹ.

Adajọ-agba na ni nigbati on gbe gbogbo ọrọ na yẹwo on ri wipe nitotọ ni ofin pajawiri na kuna lọna ti nwọn lo lati fi gba owo ori na lọwọ Williams, o si paṣẹ ki nwọn da owo na pada ati pe ki nwọn tun san owo wahala kan fun un.

## Oro Ejo Awon Awolowo Npari Die Die

EKO—Ọrọ bẹhin yọ ni iwaju adajọ Kotu-ganran, Ọgbẹni G. Showẹmimọ ti nwọn nrọ ẹjọ ọtẹ gbigbona ni iwaju re ti ẹleri kan, Patrick Ativie ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pe ni on mọ el ri Ijọba Ọgbẹni Anthony Oboh ti awọn Ọlọpa fi igbakan Pe wipe ki o wa sọrọ ni Kotu na.

O ni ara ilu kanna ni Urhomi ni agbegbe Ishan ni awọn ti wa, Ativie ni gbara ti Oboh ti ti Eko de ni o ti jẹwọ tun on wipe on ri OWO ṢE LỌDỌ awọn OLỌPA lori ẹjọ ti nwọn mba awọn Awolọwọ ro.

Ativie ni ntọọ, ririṣẹ ti on ri ṣe na ti han lara Oboh nitori pe o ti fi ile ile kan lelẹ nikiyi ni ilu awọn ti awọn alagiakọ mba kọ.

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

RA

YORUBA CHALLENGE

May–June

FUN ẸKỌ WỌNYI :

- ITỌJU OJU LỌNA ẸTỌ
- ẸKỌ NIPA ILA-ORUN NIGERIA
- ABO KURO LỌWỌ IGBẸ-ỌRIN

Iwe oloju ewe 24 yi ko lewo.

4d. pere ni iwe kan.

# ELETI—OFE

NJUWKO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. XIV. No 865 SATURDAY APRIL 20 APRIL 26 1963


# Kere O! Nwon Fe Tun Wa Ka

Awọn Yoruba ni a ki gbọ ariwo lemọ-lemọ ninu ile agbalagba ni emeji; akan ti o jẹ ki awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ pa owe yi ni irohin abẹlẹ kan ti a ngbọ wipe awọn alakoso ilu wa nmura lati tun gbogbo enia lokunrin, lobinrin, lọmọde ati lagbalagba ka jake jado gbogbo ilẹ Nigeria. A gbọ wipe awọn ti yan awọn igbimọ kan ti nwọn yio mu oju to awọn enia kika na ni igbowọ Ipinlẹ kọkan.

Boya enyin ọkawe wa ti gbagbe akan ti o ṣe ti nwọn ko fi le gba iwe awọn enia ti nwọn kọ ka ni akọkọ jade awọn kan ni awọn ara ilu kan se abumọ awọn enia wọn.

Ni ọrọ kan awọn Hausa ni awọn fura si ilu tuntun kan ti awọn Ibo ni awọn ri ni ojiji ni Ipinlẹ wọn; awọn Ibo paapa ni awọn enia ti o mbẹ ni ilu Hausa ko to gbogbo iye ti awọn pe wọn rara. Nwọn ni ki nwọn ba le ma ri aye yan awọn enia wọn pupọ wa si ile Igbimọ Apapọṣe lo fa a. Olukuluku njijadu lati jẹ Olori.

## Yoruba Nko?

Nigbati ọrọ awọn enia kika na de ile Igbimọ awọn aṣofin l'Eko ninu ọdun ti o kọja, ọrọ na fẹ bige b'a dubi, nwọn ni kilọṣe ti Minisita alamojuto eto enia kika, Alkaji Waziri Ibrahim ko tete gbe iyọrisi enia kika na jade; O ni nitori amulumọla ti awọn kaa ṣe ni.

Nisisiyi ti nwọn tun fẹ tun wa ka yi, a fi alajọbi bẹ enyin ọmọ Yoruba ti ẹ korira wipe ki nwọn ma ka awọn ọmọ nyin, ki ẹ jọwọ ki ẹ ṣe iranlọwọ fun awọn akọwe ti yio ma ka enia ki nwọn le ri awọn enia ka tọmọ tọmọ nitori ọrọ ẹhin ọla.

Bi awa Yoruba ba nfẹ ilọsiwaju fun awọn ọmọ wa, o yẹ ki a jẹ ki gbogbo agbaiye mọ iye awa ọmọ Yoruba ti a wa laye. Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi.

# Alagba Oro Na Ku Die

Awọn Babalawo ilẹ wa ni ọkan ninu awọn ODU IFA wọn wipe "eke a ma pa eleke, ọdalẹ a si ma pa awọn ọdalẹ, a da fun baba amokun so'le, ti o ni ọba aiye ko ri on. Bi ọba aiye ko ba ri, Ọba ọrun ko nwo?."

Ọrọ pọ pupọ ninu Ọdu Ifa yi, nkan ti o si jẹ ki a faa jade ni ti ọrọ Minisita alamojuto eto owo ninu Ijọba Apapọṣe l'Eko, Oloye Okotie-Eboh ti awọn kan ni ile igbimọ ni awọn fura si wipe o nlo ipo rẹ fuu owo-ṣiṣe ati pe eyi ko tọna rara, awọn si fẹ ki Alakoso Ijọba Apapọṣe baa wi ki o le jẹ ẹkọ fun awọn yoku.

A gbọ wipe kaka ki Ọlọla Tafawa Balewa ti o jẹ baba fun gbogbo wọn ni ile Igbimọ duro ki o gbo ọrọ ti nwọn fẹ sọ lori ibawi na, on ni o tun gbe iwe ifọwọ pa- lẹhin jade wipe awọn ọmọlẹhin on le ṣ'owo.

# Iwe Si Olotu

## Itan Awon Omo Oduduwa

Mo gba fun Itan Awọn Ọmọ (Yoruba) Oduduwa ti ẹ da sinu iwe Eleti-Ọfe lati inu iwe Alufa Atilade laipe yi, itan na jẹ ki ọpọlọpọ enia mọ ibiti orisun awa Yoruba ti wa.

Nitoto eyiti awọn ara wa ka itan ilu ajoji to, o yẹ ki awa ma ma tẹra mọ ati mọ ti wa.

A dupẹ lọwọ yin fun anfani ti ẹ fun wa lati le ma ri iru itan bayi ka. Oluwa majẹ ki iru awọn Alufa (Rev) Atilade tan ninu ilẹ wa, ki nwọn le ma tẹ iwe itan abalaiye fun wa.

Coutonou, Porto-Novo — Emi ni, A. Alawiye

## Oro Ejo Awon Awolowo Npari Die Die

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

O ni Simẹnti ni nwọn fi mba kọ ọ ile na kiṣe ile alabara rara.

Ẹlẹri na ni Oboh ti tun ra ilẹ oko kan jaburata ti awọn alagbapa mba pa lọwọ, ti o fẹ fi gbin nkan ọgbin si. Ativie ni Oboh alara lo fi gbogbo nkan nwọnyi han on nigbati on lọ si ile rẹ ninu oṣu ti o kọja yi.

Ẹlẹri na ni ọrẹ on pẹlu Oboh na pọ to bẹgẹ ti o jẹ wipe on ni on duro fun un lọdọ awọn ọlọpa fun ẹjọ ole kan ti nwọn mba a ṣe lọwọ ni ilu awọn.

Ativie ni bi awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ba fẹ ran enia lọ si Ghana, on alara ti on jẹ akọwe ẹgbẹ wọn ni nwọn ni lati ran, kiṣe Oboh ati Henry Oleari ekeji rẹ ti nwọn purọ ni Kotu l'Eko.

## Baba Egbe Awon Onibolu



Ọlọla Stanley Rous tiṣe Baba ẹgbẹ gbogbo awọn elere bolu afẹsẹgba ni ẹ nwo aworan rẹ yi, ni ọsẹ ti o kọja ni o ṣẹṣẹ kuro ni Dakar ilu awọn Senegal nibi ere ti gbogbo awọn enia dudu ṣe laipẹ yi. On alara paapa ni on gba fun ere awọn ara wa na.

## Oro Olotu

Ọrọ na ku diẹ ki a to. Iyẹn ni pe Minisita alamojuto eto ọkọ le da owo pọ pẹlu awọn onimọto kan ki on na ra mọto jọ jaburata lati mọ fi kọ ẹru lọ si Asaba? Inilara ni eyi jẹ fun awọn ara ilu.

A ko wipe ki awọn Minisita wa pa iṣẹ-owo ti nwọn ba ti nṣe rẹ ti nwọn ba ti fi nwọn si ipo alamojuto iṣẹ Ijọba, ṣugbọn ki nwọn maṣe gbidanwo lati da omiran silẹ ni akoko ti nwọn ba nṣe alamojuto iṣẹ ilu. Egungun ti a ba so mọ aja lọrun, aja ko gbọdọ sa na n.

Alagba, ọrọ na ku diẹ ki o to.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(Lati Owo Ayiluka)

## Apejo Ijo Baptist

Mo ki gbogbo awọn ikọ ti awọn Ijọ kọkan ran wa si Apejọ Ijọ awọn Ṣọṣi Onitẹbọmi (Baptist Convention), l'Eko wipe nwọn ku abọ; mo si ki awọn Ijọ Ṣọṣi na ti nwọn 'wa ni Eko, Ebute-Mẹtta, Yaba ati Apapa ti nwọn gba wọn ni alejo pe nwọn ku alejo. Mo gbọ wipe lẹhin ipade yi awọn ara Ghana ko ni ba wọn pejọ ni Nigeria mọ, awọn na yio ma ṣe ti wọn ni ilu awọn Aganyin.

Ko buru, ṣugbọn o yẹ ki a jọ ma ṣe ọmọlẹbi Ṣọṣi ni ẹkọkan ni ọdun meji meji ki a le ma jọ gbadura pọ.

## Adie Ye Pepeye

Mo ri enmọ ni Idita ni ọjọ Ọjọ'Bọ, adiẹ kan pa pẹpẹyẹ ni adugbo ti nwọn npe ni Idita l'Eko. Ọrọ na ya mi lẹnu pupọ, ṣugbọn awọn agbalagba ni o nidi. Nwọn ni bi ija ba de, bi adiẹ ko ba le wẹ odo ja, pẹpẹyẹ a gbe e. Ọmọ pẹpẹyẹ marun ni adiẹ na pa, iṣoriị(good luck) ni o jẹ fun awọn ara Olowogbowo lati oke de ilẹ.

## Agoro Bogun Bo'lu

Ọpọlọpọ yin ti o ba mọto kọja ni ijẹjọ l'Ebute-Mẹtta ni Agọ Ẹgba ni eti Apena ni ẹ ṣe akiyesi wipe mọto yin ko tete ri ọna gba kọja. Ko si ewu, ọmọ tuntun kan ti arakunrin wa, Ọgbẹni Ladi Agoro bi ni a nko jade. Boya ẹnyin ọkawe mi niran nkan ti mo sọ fun yin laipẹ yi nipa Iyaanfin wa, Abiba Oshodi (Iya Kari) pe o fẹ dabira fun aburo rẹ, Tayibatu Aramide ti o ṣẹṣẹ bi ọmọ fun Ọgbẹni Agoro an. Ọjọ ikomọjade na lo de.

Ikemọjade na pabambari ni Ebute-Mẹtta. Agoro fọmọyọ. Agoro-Bọ'gun-bọ'lu, ẹ ku inawo, inawo yi mu emi Ayiluka niran eyiti Ọgbẹni wa, baba rẹ ṣe ni adugbo yi kanna ni Ebute-Mẹtta ni iwọn nkau bi ọgbọn ọdun sẹhin, gbogbo awọn ara Eko ati ara Ibadan ni o pe sibẹ, emi na ba wọn jo ijo igba ti o wa lode lọjọ na. Ni..u awọn ti o fowo yẹ mi si lọjọ na ni Ologbe Mọjidi Animashaun, ọrẹ kori-kosun ni on pẹlu Ọgbẹni wa lọjọ na lọhun. Ivẹn lo jẹ ki nwipe o fa ọmọ ọkọ yọ.

Ọmọ tuntun jojolo na, Kalifat Fifẹlọmọ, nkọ? Ṣe alafia ni o wa ? Ọlọrun jẹki o ni ọọwọ lẹhin o. E ku inawo.

## Mope Turner, O Digbere

Nwọn ni ibi ẹlẹkun gbe nsọkun ni awọn alayọ nyọ anu ṣe mi pupọ lati gbọ wipe ọrẹ mi, Ọmọpẹ Turner jalaisi ni ile awọn obi rẹ ni 27, Daddy Ọbọsọ Lane, l'Eko ni ijẹfa. Iku Mọpẹ yi ba mi lẹru pupọ, o si jẹ ki ntun niran iku aburo mi, Ologbe Tunde Joseph ti o jalaisi ni aipẹ yi nitoripe ọrẹ rẹ niṣe, gbogbo wa ni a si jọ sin oku Tunde na.

Iku Mope t.. je ki nn... igba aiye ... l'Eko ti a ma nṣere ọlọmọde ... awọn bi Ọgbẹni Tunji Kester tiṣe ọg...wọ Ọlọpa ni Ipinlẹ Iwọ Orun nisisiyi.

Ọmọ Ẹgba ni Shokẹ..u ni baba J.O Turner ti o bi Mọpẹ, baba rẹ na si jẹ ọkan ninu awọn gbajumọ onifari l'Eko nigba aiye rẹ.

Mo ki gbogbo awọn ẹbi ologbe na, awọn bi aburo rẹ, Sholankẹ, Latoun (ọmọ Adigun, tiṣe iyawo rẹ alarede), ẹgbọn rẹ, Iyaafin Adelaice Mọwo Shobande, Moses Adetunji Williams, Theophilus Adeoye Williams pelu awọn ebi Cole ati ọmọ rẹ Jide ti o wa ni ilu Oyinbo, nwọn ku ajalu na. Ọlọrun ki o mọṣe ni tele—tele.

Mọpẹ Turner, o di gbere, o di arinnako.

# Isinku Abibu Olorin Pabambari l'Eko

EKO — Ẹyẹ isinku Ologbe Abibu Oluwa Olori awọn elere sakara ti a tufọ rẹ fun yin ninu iwe wa ti ọsẹ ti o kọja dun pupọju, o si pabambari. Ni adugbo ti nwọn npe ni Idumọta nibiti nwọn nti Tolotolo ni ile awọn ologbe na, ni nwọn ti ṣe isinku na.

Ki a kọ bẹrẹ irohin wa ni ọjọ ti awọn ngbe ologbe Abibu na lọ si itẹ lati sin, irohin ko to afọjuba ni ti ọjọ na, awọn ẹnia dabi omi, awọn oni mọto ko jẹ ki a mọ awọn oni kẹkẹ basikulu,

Nigbati o ku bi Ereko si Oju Ọlọbun ni awọn ọmọ-erinwo (awọn ọmọluwabi) ti o tẹ le kẹkẹ oku na ti gbe posi rẹ kuro ninu mọto, ti nwọn ru u, ti nwọn berẹsi kọ orin ẹyẹ ti Ologbe na ma nkọ nigba aiye rẹ.

Lemọmu (Alhaji) Mọsalasi Onitolotolo ni Idumọta ni o ṣe eto isinku na ni itẹ.

Ni ọjọ ti nwọn nṣe ẹyẹ ikeyin (ti awọn ara Eko npe ni SITTING SUNDAY) gbogbo oriṣiriṣi ọmọ ẹgbẹ ni nwọn kan bẹ ti olukuluku si nnawo bi ẹleda. Akọbi Ologbe na ti nwọn npe ni Muinatu ati awọn iyawo ile si nfi tẹyẹ tẹyẹ ki gbogbo wọn kiri.

Awọn ẹgbẹ ti o wa sibẹ pọ ti a ko le daruko gbogbo wọn tan ni ikọkan.

A ki ẹnyin ọmọ ati ẹbi oloku, ẹ ku aṣẹhinde.

# AKIYESI

**A ki gbogbo enyin Onkawe wa pe E ku ipalemo Odun Ileya, emi a sopo e, ki Olorun jeki a se odun na pelu alafia. Ki e se ireti pe a o fun yin ni irohin kikun nipa awon Alhaji wa ti odun yi ati opolopo alaye nipa odun Ileya na.**

# Bi Ere Sakara Se Bere

kọ ko ilu-sakara wọ Eko ati Abeokuta, awọn ara Ibadan ko kọ tete gba.

Awọn Imale Yoruba Eko ati ti Abeokuta fẹran a nṣe ẹyẹ Mo-kewu-ja (W limọ) ni ọ..a repete pupọ, iyẹn wa mu ki a w ọ n Alufa ilekewu (awọn baba Ilọrin) ma nu awọn oniwaka ti yio ma yonbo ọmọ oniwolimọ, iya rẹ pẹlu baba rẹ fun owo ti nwọn na lori ọm wọn ti o K eweja.

**Ilorin Baba Ngeri**

B: awọn ba ti mọ eleyi ẹ to ni awọn obi oniwolimọ na a ṣe na o..o fun wọn to; Nwọn a si tun fun awọn oni waka yi ni onjẹ jẹ lọpọlọpọ, fere KAKAKI a ma dun kanran; ẹniti o ba mọ ijo jo, a ma jo, ẹniti ko ba si mọ ijo jo a ma mi titi bi koriko inu oko.

Nigbati o pe awọn baba oni kakaki oni-waka yi wa ṣe akiyesi wipe awọn kan wa ninu awọn Imale Yoruba ni ẹsẹ-odo ti nwọn fẹ ilu faaji abẹ ile ti nwọn ba nṣe aṣeyẹ igbeyawo.

**Baba Olohun Iyo**

Nigba aiye atijọ, aṣeyẹ igbeyawo ni awọn Yoruba Imale ma nṣe pẹlu a o awọn ki pariwo oku wọn gbogbo nkanna ko dabi; t ye isisiyi ti aiye ti lu ja ara nwọn lọ un losi. Faji abẹ ile yi lo jẹki awọn ara Ilọrin ko a..n AKIGBEMARU onilu igba wọ ilu.

Elere Onigba ni a n p e awọn oni sakara yi ni akọkọ ti nwọn kọ gbe igba ti nwọn ndoju rẹ delẹ wọ'lu wa. Ẹ jẹ ki kan awọn nkan elo ti nwọn nlo fun orin kikọ wọn fun yin nigbana, ekini igba ademu merin, molo (ti a npe ni guitar ni aiye ode isisiyi) ati ilu "Kanango" pẹlu baba kan ti o ba ni ohun ti o dun daradara. On na ni o ni lati ma da gbogbo orin ti nwọn a ma kọ lagbo na tabi ti yio ma ki awọn ti o ba fẹ ki ni awujọ. Ni ọrọ kan, baba olohun iyọ yi ni olori awọn oni sakara na nibikibi ti nwọn ba gbe lọ ṣeyẹ.

Ẹnikẹni ti o ba nlu ilu ti awọn oni sakara na npe ni "Kanango" n i lati jẹ ẹniti o fara balẹ ki o si mọ tẹle ohun ti baba olohun iyọ Olori wọn ba nwi; baba olohun iyọ yi ni ma nta MOLO.

Bi olori awọn oni sakara yi ba ti mọ MOLO ta to ni ere rẹ yio fi ma dun to, o si ni lati jẹ ẹniti o ni iye ninu t i o l e tete nii an nkan gbogbo, yala orukọ enia ni tabi oriki tabi iyewo ti Oluwarẹ ti gbe tabi oye ti awọn iran re ti jẹ.

Ariwo ilu 'kanago' ti nwọn ba nlu ni ibi ere sakara ko gbọdọ [illegible]rọ ,u ti MOLO lọ ki awọn enia le ba ma gbọ nkan ti baba olohun iyọ ba nwi. Gbogbo nkan ti olori wọn yi ba nwi ni gbogbo awọn baba ti nlu igba ni lati ma ba wi pẹlu ni kiakia.

Awọn ara Ilọrin ti nwọn ko ilu sakara yi wọ ilu fi lu na pa owo lọdọ awọn enia wa fun ọdun gbọrọ ki awọn enia wa paapa to ja aṣa ere sakara na mọ wọn lọwọ.

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)

# Awon Iwe Asiko

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

o ti fi owo yi pamọ ti ku ni ọjọ pipẹ, awọn ọmọ rẹ ko si mọ ibo ni o fi owo rẹ pamọ si. Awọn ẹlomiran nfi owo wọn ra ẹru ẹru yi ama ṣiṣẹ fun wọn ni ipo owo wọn. Eyi yi jẹ ọna ti ko dara, nitoripe Ọlọrun da gbogbo enia ni ominira, ko si fẹ ki a fi ẹnikan ṣe ẹru.

A tun ri awọn ẹlomiran ti nwọn nfi owo wọn ya iwọfa. Eyi yi ni pe olowo kan yio ko bi Poun marun (ogun ọkẹ) fun ẹnikan ti owo npọn loju. Eleyi yio mu ọmọ rẹ ọkunrin tabi obinrin ti o to iṣẹ ṣe wa fun olowo yi. Ọmọ yi yio si ma sin fun ele ti o ni lati ma gun eri owo yi,

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)


# JAPANESE BICYCLES



• STRONG
• SPEEDY
• SMART

TODAY
JAPANESE BICYCLES COVER
THE WHOLE WORLD

For import informations apply to :

JAPAN BICYCLE
TRADE CENTER
P. O. Box 4117, BEIRUT LEBANON
CABLE EXBIKE BEIRUT

# U.S.Publish New Handbook On Africa For Exporters

WASHINGTON, (U.S.A.)—The U.S. Department of Commerce has published, 120 page handbook titled "Africa-Sales Frontier for U.S, Business" to help American exporters and investors participate in Africa's economic development.

The book was described by the Commerce Department as "an on-the-spot practical assessment of opportunities and pitfalls involved in trading in selected African countries."

"It discusses the export outlook in Africa by regions, selecting those countries where opportunities for trading are foremost and contrasting these with other where institutional bariers and obstacles stand in the way," the Department said.

Prepared under the direction of Bernard Blankenheimer, Director of The Africa Division in the Department's Office of International Regional Economics, the book contains articles on 18 different African countries. The were written by Commercial Attaches and other U.S. foreign service officers in Africa. The book lists all the independent African states and their government offices in the United State. Some 4 photographs from Africa are included, along with 13 maps of Africa areas, a statistical apprendix, and a bibliography of reference courses aimed at stimulating the American business community to make a further study of African markets.

Mr. Blankenheimer described the book as representing the latest "tangible evidence of the American government's effort to economic development."

Eugene M. Braderman, Director of the Department's Bureau of Internationa Commerce, noted in the book's introduction that the American business community "needs to be kept informed of all aspects of African development."

"Past patterns of African production and trade are being drastically altered," he said. "New urban communities are springing up and large-scale development projects in mining.





Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS: (EB): IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT: ABA

SUB-DISTRIBUTORS

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

## Enahoro Mbo Si Ile Yi Ni Dandan

LONDON—A ri waya kan gba lodo akowe onirohin wa kan lati ilu Oyinbo ni oru oganjo ana wipe awon adajo agba meta ni Kotu-gaaran ilu London ti tun pase wipe ki nwon da Oloye Anthony Enahoro tise igbakeji baba egbe Afenifere (AG) pada ni dandan ki o wa si Eko wa je ejo ote ti awon olopa ni nwon di si Ijoba ilu Nigeria.

Ni Kotu-ganran ilu Oyinbo na ti nwon npe ni Queen's Bench Division ni ana, awon adajo agba amofin meta ni nwon joko se ejo Oloye Enahoro ti awon Ijoba Apapose ile Nigeria pe ni isansa ati alarinkiri.

Olori awon adajo na, Olola Parker ni ko si eniti ko kanu Oloye Enahoro fun nkan to de ba a yi sugbon awon ti wipe nkan ti o tona ... pe ki o pada ... ilu re.

Adajo-agba ... na ni ko ese wipe ejo ti nwon kan ti da lori ... awon tele rara, awon ... ti awon loto ni.

Loya Enahoro ni on ti ngbero lati tun gbe ejo na lo si iwaju apejo awon olola (House of Lords) sugbon awon ogunnagbongbo a ajo na ti fonmu wipe ki ejo na ko duro nibiti awon gbe da a si yi.



Chief A. Enahoro

## Ikomo Ladi Agoro Dun

EBUTE - METTA— Irohin ko to afeji ba ni eye ikomojade alarintin ti Ogbeni Ladi Agoro se lori omobinrin jojolo ti iyawo re, Tayibatu Aramide bi fun un ni aipe yi. Ni Olopo Lagos Street mo adugbo ti gbogbo vin mo' oruko ni Strachan Street ti nwon so di Herbet Macaulay Road ni awon tise aseye ikomojade na ni ijejo.

Ki o to to akoko ti nwon fi aseye na si ni asale ni ese awon enia jankanjankan ti npe sibe lokunrin ati lobinrin pelu awon pelu awon Oyinbo ti nwon je ore baba omo tuntun na.

Iya omo tuntun na paapa pelu awon ore re ro aso igba nwon si nnawo bi eleda bena si ni egbon iya omo na ti o nje Abibat Oshodi ti o nta aso ni oja gota Ereko l'Eko na wabiwosi owo.

Gbogbo awon omo egbe MESO tise awon sanmori obinrin ilu Eko ni nwon pe so sibe siba siba. Nigbati o di ale gbogbo ese awon omo egbe Island Club ni o pe sibe pelu awon Oloye ati awon olola ilu Eko.

Oluwa ki o da omo na si fun awon iya ati baba re

# Awon Irin-Ajo Gomina



**Aworan egbe yi ni igba ti Gomina agba Olola Dokita Nnamdi Azikiwe rin irin ajo lo si Shagamu ni ose yi, Omoba Adeleke Adedoyin ni o wa ni apa osi Gomina na ti o wa lari aworan na pelu Oba Awolesi Akarigbo Iiebu Remo ni apa keji yi.**

... Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Box 467, Phone 23370 Editor, (Olotan ...) Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos.